# Orin Kúlúńbú: Ọ̀nà Ìfinisẹ̀fẹ̀ àti Ìjánu Àwùjọ ní Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn Yewa

**Wahab Adegbayi IBRAHIM Ph.D.***
ORCID iD https://orcid.org/0009-0001-0106-8707

**ÀṢAMỌ̀**
Ṣaájú kí àwọn Òyìnbó tó dé ilẹ̀ Adúláwọ̀ pàápàá ilẹ̀ Yorùbá, onírúurú iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-ìpohùn ni ó wà ní agbègbè kọ̀ọ̀kan tí wọ́n sì máa ń wà bí ohun ìdámọ̀ fún agbègbè tí wọ́n bá ti ń lò wọ́n. Ọ̀kan nínú àwọn iṣẹ́-ọnà ajemọ́-ìpohùn yìí ni orin jẹ́ láàárín àwọn ẹ̀yà Yorùbá, ó sì wà fún ìnàjú, ìdánilárayá àti ìkọ́nilẹ́kọ̀ọ́. Èyí ni ó máa ń mú kí àwùjọ àwọn Yorùbá ní ìfẹ́ sí orin kíkọ níbikíbi, nígbàkúùgbà àti lórí ohunkóhun. Ọ̀kan nínú àwọn orin ìbílẹ̀ Yorùbá tí ó gbajúmọ̀ láàárín àwọn ènìyàn ìlú Ọ̀jà-Ọ̀dàn ni orin Kúlúḿbú tí ó jẹ orin ajemọ́-eré-oníṣe, tí ó sì tún jẹ mọ́ ìfinisẹ̀fẹ̀. Ìlépa iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àfihàn orin Kúlúńbú ní ìlú Ọjà-Ọ̀dàn gẹ́gẹ́ bí ọnà ìṣèré ìpohùn Yorùbá, kí a ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn àkóónú rẹ̀, kí á sì tọ́ka sí àwọn irúfẹ́ ọnà ìfinisẹ̀fẹ̀ inú orin yìí pẹ̀lú ọ̀nà tí ó ń gbà fọ àwùjọ mọ́. A ṣe àkójọ àwọn orin Kúlúḿbú tí a lò ní ìlú Ọ̀jà-Ọ̀dàn ní agbègbè Yewa ní ìpínlè Ogun ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. A ṣe òfintótó ìṣèré orin yìí, a sì kópa nínú ìgbékalẹ̀ orin náà. A ṣe àfàyọ àwọn àbùdá eré-oníṣe àti ọnà ìfinisẹ̀fẹ̀ tí ó ń jẹ yọ nínú àgbékalẹ̀ orin Kúlúḿbú àti ipa rẹ̀ lórí àwọn ènìyàn àwùjọ. Iṣẹ́ yìí ṣe àfihàn àwọn ẹ̀yà Yorùbá Yewa gẹ́gẹ́ bí alárògún àti oníṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-ìpohùn, ó sì tọ́ka sí bí wọ́n ṣe ń lo orin Kúlúńbú fún ìtọ́sọ́nà ètò ìgbé-ayé wọn, ọ̀nà ìjánu àwùjọ àti fún ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Iṣẹ́ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, iṣẹ́-ọnà láàárín àwọn Yorùbá ń dàgbà sókè lójoojúmọ́ àti pé ìyípadà ọ̀tun ni orin Kúlúḿbú ń mú bá agbègbè tí ó ti ń wáyé. Èyí ni ó sì yẹ kí ó jẹ́ àwòkọ́ṣe fún àwọn oníṣẹ́-ọnà káàkiri ilẹ̀ Yorùbá àti gbogbo àgbáyé.

Before the arrival of white-men in Africa, most especially Yorùbá land, there were numerous Yoruba verbal arts which serve as symbol of identity of each communities. Song is one of these verbal arts among Yorùbá people and it is purposively for enjoyment, entertainment and moral teaching. This is why Yorùbá people have much interest in singing at anywhere, anytime and on anything. One of Yorùbá traditional songs that is popular among Yorùbá people of Ọ̀jà-Ọ̀dàn is *Kúlúńbú* song which is a dramatic and satirical song. The focus of this paper is to showcase *Kúlúńbú* song in Ọ̀jà-Ọ̀dàn as a form of Yoruba oral performance, analyse its thematic contents, identify its satirical styles and examine its social purification concepts. The *Kúlúńbú* songs were collected from Ọ̀jà-Ọ̀dàn, Yewa area, Ogun state. The performance of the songs was investigated with the researcher's participation in the presentation. The dramatic features and satirical styles of *Kúlúńbú* songs and its effects on the society were identified. This work portrays Yewa Yorùbá people as philosophical verbal artists and also shows how *Kúlúńbú* song is being used for guidance and development of their society. This work concludes that verbal art among Yorùbá people is growing time to time, and *Kúlúńbú* songs facilitate positve change in the society. This is the reason it supposed to be seen as exemplary form for other verbal artist in Yorùbáland and the world at large.

## Ìfáàrà
Àfojúsùn iṣẹ́ Ìwádìí yìí ni orin kúlúmbú ọ̀na ìfinisẹ̀fẹ̀ àti ìjánu àwùjọ ní ìlú ọjà-ọ̀dàn Yewa. Onírúurú àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí orin láwùjọ Yorùbá ṣùgbọ́n àkíyèsi fi hàn pé iṣẹ́ kò

* Department of Yorùbá StudiesTai Solarin University of Education, Ìjagun, Ìjẹ̀bú-Òde, Ogun State, E-mail: Nigeriaadegbayiwahab@gmail.com

tí pọ̀ lórí orin kúlúmbú ní agbègbè Yewa. Àkíyèsi fi hàn pé àwọn onímọ̀ tí wọ́n ṣe iṣẹ́ lórí orin ní agbègbè Yewa tẹpẹlẹ mọ́ orin bọ̀lọ̀jọ̀ ju àwọn òmíràn lọ. Èyí ni ó wá gún wa ní kẹ́ṣẹ́ inú láti ṣe àfihàn orin kúlúmbú àti ipa tí ó ń kó lórí ìdàgbàsókè Yewa lápapọ̀. Oríṣìíríṣìí àwọn ìṣèlẹ̀ àwùjọ ni ó sáábà máa ń jẹ́ àkóónú fún orin kúlúmbú, àwọn àkóónú náà ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí i ọ̀nà ìdàgbàsókè tí orin kúlúḿbú mú bá Ọjà-Ọ̀dàn ní agbègbè Yewa. Àwọn àṣà Yorùbá bí i àṣà ìgbéyàwó, oge ṣíṣe, òrìṣà bíbọ, ọ̀ré níní, òkú sísin àti okoòwò ṣíṣe pẹ̀lú onírúurú orin àti ọdún Ìbílẹ̀ tó ń fi ìgbàgbọ́ ìṣe àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá hàn sodò sí inú àwùjọ àwọn ará ọjà-ọ̀dàn. Ní pàtàkì jù lọ ohun tí a fẹ́ gbéyàwò nínú iṣẹ́ ìwádìí ni láti wo ọ̀nà ìṣeré orin kúlúmbú àti ọ̀nà tí àwọn asèsínijẹ ń gbà ìfinisẹ̀fẹ̀ àwọn ẹ̀dá àwùjọ láti fi ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdániláràyá.

**Aáyan Ọ̀mọ̀ràn lórí Orin**

Oríṣìíríṣìí àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti sisẹ́ lórí orin. Lára wọn lati rí CMS (1913:121) nínú Awolusi (2012:29), Ọláwálé (2015:81), Beier (1956:23), Vidal (2012:55), Rájí (2015:23), àti Lámínà (2023).

CMS (1913:121) nínú Awolusi (2012:29) sọ pé 'músíìkì' jẹ́ orin. Awólúsì nínú ìwòye tirẹ̀ gbà pé, músíìkì ju orin tí CMS pè é lọ, nítorí pé músìíkì ní ìlò tìlùtìfọ̀n nínú ju orin kíkọ lásán lọ. Ni ìwòyè tèmi, músíìkì jẹ́ orin. Awólùsì gbà pé kì í ṣe wí pé orin kíkọ kò ní ìlò tìlùtìfọ̀n nínú rara, tí ó jẹ́ wí pé kò kàn tó ti músíìkì ni gẹ́gẹ́ bí ó ti wòye. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ ní ìwòye tèmi, nítorí pé ìyàtọ̀ wà láàárín wọn. Músíìkì àti orin kì í ṣe àmúlò tìlùtìfọ̀n gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ yìí ti wí, músíìkì gan-an ni tìlùtìfọ̀n. Lóòótọ́, orin lè jẹ yọ nínú músíìkì bí ìpìlẹ̀ tìlùtìfọ̀n fún àwọn tó fi ń ṣe àríyá. Ìdí ni pé, kì í ṣe gbogbo orin ló máa ń ní tìlùtìfọ̀n nínú àgbékalẹ̀ rẹ̀. Bí abiyamọ bá ń kọ orin arẹmọ, kò pọn dandan kí ó ní tìlùtìfọ̀n.

Èrò Scholes gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wa nínú Ọláwálé (2015:81) ni pé "song is a natural means of self expression". (Orin jẹ́ nǹkan àdámọ́ tí a fi máa ń gbé èrò ọkàn ẹni síta.) Beier (1956:23) sọ pé:

> There is no occasion in Yorùbá life that is not accompanied by songs. Birth, marriage, house warming and funeral dirge are all occasions for lyrical songs of great beauty. Everyday life is also accompanied by a great deal of impromptu singing, a kind of musical thinking in which the singer puts everything to a tune which happens to pass through his head.
>
> (Kò sí ayẹyẹ kan ní ilẹ̀ Yorùbá tí wọn kì í fi orin kkọ ṣe ìrànwọ́ fún. Ìkómọjáde, ọ̀jọ-ìbí, ìgbéyàwó, ìṣílé àti ètò ìsìnkú lọ́kọ̀ọ̀kan ni wọ́n jẹ́ ayẹyẹ tí orin kíkọ máa ń buyì kún. Lójoojúmọ ayé ni orin kíkọ lọ́kan-ò-jọkan máa ń jáde láìròtẹ̀lẹ̀, nínú èyí tí ọ̀kọrin máa ń fi ìpohùn gbé e kale tí ó si gbà ìrònujinlẹ̀ gìdí kí àgbèkalẹ̀ rẹ lé létó tí ó mọ́yan lórí.

Yàtọ̀ sí wí pé Bier (1956:23) fi àwùjọ Yorùbá àti ètò ìgbé-ayé wọn hàn gẹ́gẹ́ bí èyí tí o kún fún orin kíkọ, ó tún ṣe àfihàn ipa àti ipò tí orin kó nínú ètò ìgbé-ayé àwọn Yorùbá. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ wí pé orin ti di bárakú fún àwọn Yorùbá. Ó tún fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé ojoojúmọ ayé ni orin kíkọ máa ń wáyé láwùjọ Yorùbá tí o si lé jẹ́ ti àìròtẹ́lẹ. Ìyẹn ni pé, àwọn Yorùbá ni ẹ̀bùn orin kíkọ láti ọrun wá tí ó máa ń ṣẹ́yọ lára wọn ni gbogbo ìgbà. Vidal (2012:55) náà fi èrò tire nípa orin hàn nìgbà tí o sọ pé:

> Throughoout history, music has been one of the most common forms by which man expresses his emotions, feeling and sentiments. The primordial man used music

> to express fear, pain and anger. Music was an important part of oriental mysticism. The various people living in Nigeria are not exceptions. They use music to express the value of their institutions, communities and culture… music is partly the means by which social control is maintained in the society.
>
> (Láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni tìlùtìfọn tí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí ọmọ ènìyàn fi máa ń fi ìmí-ẹ̀dùn àti èrò ọkàn ẹni han. Àwọn ará ìgbà ìwáṣẹ̀ lo orin láti fi ìbẹ̀rù, ìnìra àti ìbímú hàn. Tìlùtìfọn jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára nnkan àṣírí ni àgbáyé. Èyí kò si yọ onírúurú àwọn ènìyàn Nàìjíríà náà sílẹ̀. Wọn máa ń lo orin láti fi pàtàkì àgbékalẹ̀, àwùjọ àti àṣà wọn hàn… Tìlùtìfọn sì tún jẹ́ ọ̀kan lára ohun èlò ìkóra-ẹni-níjánu láwùjọ)

Ohun tí àyọlò òkè yìí fi ń yé wa gẹ́gẹ́ bí èrò Vidal ni pe tìlùtìfọn tiwá pẹ̀lú ọmọ ènìyàn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹpẹ ayé wá. Rájí (2015:23) gbìyànjú láti tún fún orin ni oríkì. Ó sọ pé:

> Orin ni a lè pé ní ìfohùndárá tó ní ẹwà ìpèdè bí àwìtúnwí, àfíwé àti ìgbésẹ̀ dọ́gbándọ́gba lọ́nà tí a lè wọ ohùn nílẹ̀ ní èyí tí yóò fún wa ní bátàni tàbí òté kan tí kò ni jẹ kí orin sú ènìyàn gbọ́ tí ó sí ni ìtumọ̀, tí o tún jẹ ìtẹ́wọ́gbà fún àwọn ènìyàn àwùjọ. A lè lu ìlù sí i, a sì lè kọ ọ́ lọ́bọ̀rọ́.

Gbogbo àwọn onímọ̀ tí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ wọn ni wọ́n tisọ ohun tí wọ́n léró pé orin jẹ́. Ọ̀pọ̀ ni wọ́n dàbà àwọn àbùdà tí ohun tí a pè ní orin gbọ́dọ̀ ni. Lámínà (2023) náà sișé lórí kókó-ọ̀rọ̀ àti ìṣọwọ́lò-èdè fún ìdàgbàsókè àwùjọ nínú àṣàyàn orin Jùjú Ebenezer Obey àti ti Sunny Adé. Ó ṣàlàyé pé ‘Orin ni ohùn ẹnu tàbí èlò tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde ni ọ̀nà ara, tí ó ni ìpèdè àti ìgbésẹ̀ dọ́gbà-ń-dọ́gba, ó lè ni ìtumọ̀ tàbí kí ó má ni. Pẹ̀lú èrò awọn onímọ̀ yìí orin ìpèdè tí ó yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ẹnu lásán, ó gbọdọ̀ ní ìtumọ̀ àti iṣẹ́ tí ó fẹ́ jẹ́ fún awọn ènìyàn àwùjọ.

**Orin kúlúmbú**

Orín kúlúmbú jẹ́ orin tí wọ́n máa ń fi àrògún àti àròjinlẹ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ ní Ọjà-Ọ̀dàn lágbègbè Yewa. Ìwádìí tí a ṣe fi hàn pé orísun orúkọ orin kúlúmbú yìí wáyé látàrí ọ̀nà tí wọ́n ń gbà jó ijọ́ orin kúlúḿbú. Àkíyèsí fi hàn pé, nípa kíko-mọ́lẹ̀ jó orin yìí ni wọ́n fí pè é ní orin kúlúmbú ( kú+lu+m+bú) Ìlú kétu ni orin Kúlúḿbú ti hù jáde, àwọn Ọ̀họ̀rí Kétu ni ó dá ẹgbẹ́ yìí sílẹ̀. Ìwádìí jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé, Bàbá Ọládìtàn àti Ọba Àdìsá ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ orin yìí ni ìlú Ọjà-Ọ̀dàn. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ orin yìí gẹ́gẹ́ bí i ẹgbẹ́ olórin. Olórí ẹgbẹ́ olórin yìí tí ó ń jẹ́ Ọba Àdìsá jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé láti ara ijó tí wọ́n ń jó nílùú tí wọ́n ń pè ní Àkúbà, síto àkúbè àlẹ̀mọ́ ni orin Kúlúḿbú ti jáde. Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, Ọba àdìsá sọ pé, ohun tí ó mú àwọn se ìwádìí ni pé, bí gbogbo àwọn orin tí a dárúkọ sí òkè yìí, yóò ṣe máa jẹ́ orúkọ kan ṣoṣo àti bí ọ̀nà tí àwọn yóò gbà ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ tí yóò fi yàtọ̀ sí àwọn èyí tí a sọ sẹ́yìn ni àwọn fi sọ orin yìí ni orin Kúlúḿbú. Orin Kúlúḿbú jẹ́ orin tí wọ́n máa ń jó ijó rẹ̀ ni àjólàágùn nítorí gbogbo ara ní wón fí ń jó ijó yìí . Bàbá ẹgbẹ́ orin yìí ni wón pè ní "Bàbá ẹgbẹ́" Obìnrin tí ó jẹ́ olórí Kúlúḿbú ni wọ́n pè ní ìyá ẹgbẹ́, Bàrúwá ni wọ́n ń pe ẹni tí ó bá ń lé orin. Ìwádìí fi hàn pé orin yìí ti pẹ́ púpọ̀, ṣùgbọ́n nǹkan bí i ogójì ọdún sẹ́yìn ní wọ́n dá ẹgbẹ́ orin Kúlúḿbú sílẹ̀.

Orin kúlúmbú wà fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá ní ìlú ọjà-ọ̀dàn ní agbègbè Yewa. Kò sí ẹni tí kò le è kọ orin kúlúmbú. Ọmọdé lè kọ orin yìí pàápàá fún ìnàjú. Ìwádìí tí a ṣe fi hàn pé

orin kúlúmbú jẹ́ àkójọpọ̀ àwọn orin bíi àkúbà, Àlémọ́, sìtò àti gàgàló ni ó daràpọ̀ tí ó di orin kúlúmbú. Àwọn orin tí a dárúkọ yìí wọ́n sì tún ko wọ́n di òní ní ìlú ọjà-ọ̀dàn, ṣùgbọ́n ara wọn ni orin kúlúmbú ti jáde. Èyí fi hàn pé láti ara orin àkúbà, orin kete, sító àti gàgàló ni a ti ṣe àfàyọ orin kúlúmbú. Ní ìlú ọjà-ọ̀dàn, ó ní àwọn ọmọdé tàbí àgbàlagbà tí wọ́n mú orin yìí gẹ́gẹ́ bí i iṣẹ́ oòjó wọn. Bí ayẹyẹ kan bá wáyé tàbí tí wọ́n bá ń ṣe ọdún kan, wọ́n máa ń pe àwọn ẹgbẹ́ olórin kúlúmbú láti dá wọn láràyá. Àwọn ẹgbẹ́ olórin kúlúmbú yìí kò sí ọ̀nà tí wọ́n kò lè gbà fi ni ṣe ẹ̀fẹ̀, bákan náà ni pé kò sí ẹ̀dá àwùjọ kan tí wọn kò lè fi ṣe ẹ̀fẹ̀. Wọ́n lè fi babaláwo ṣe ẹ̀fẹ̀ láti ara ìwà tí ó hù, wọ́n lè fi àfáà ṣe ẹ̀fẹ̀ láti ara irú ẹ̀dá tí ó jẹ́. Bákan náà ni wọ́n lè fi pásítò ṣe ẹ̀fẹ̀ láti ara ìwà kan tí ó ti hù séyìn nínú ìlú. Àwọn àkóónú orin wọn máa ń ní í ṣe pẹ̀lú ìwà ìbàjé, ọ̀rọ̀ ìyànjú, ìwúre, ètò ọrọ̀-ajé, ètò ìṣèlú, ọ̀rọ̀ èsìn, ètò ẹ̀kọ́, Ìbára-ẹni-gbépọ̀, ètò amúlùúdùn àti onírúurú nǹkan tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ nínú àwùjọ.



**Àwòrán Olóyè Ṣéríkí ti Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn**
**ORÍSUN-ÌMỌ̀: Oko Ìwádìí Olùwádìí ní Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn (05-01-2025)**

**Èèwọ̀ orin Kúlúmbú**

Èèwọ̀ ni òfin tàbí òte tí a fí mú nǹkan láti máa ṣe nitori igbáyé gbádùn ẹ̀dá. Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ wí pé, kò sì àwùjọ tàbí ẹgbẹ́ kan tí ó wà ní àwùjọ Yorùbá ti wọn kò ní òte tàbí òfin tí ó gbé wọn ró. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni Èèwọ̀ yìí nínú ẹgbẹ́ kúlúmbú láti lè jẹ́ kí ó máa tè síwájú bí-ó-tí-tọ́ àti bí-ó-ti-yẹ . Lára Èèwọ̀ tí ó jẹ́ àkókò nínú orin kúlúmbú ní pé, àwọn tí wọ́n jọ jẹ́ ẹgbẹ́ akọrin kúlúmbú wọ́n kò gbọdọ̀ gba ìyàwó ara wọn. Bí ẹnì kan bá ṣe èyí láàárín wọn, wọ́n yóò yọ ọ́ kúrò nínú ọmọ ẹgbẹ́. Yàtò fún èyí irú ẹni yìí ni wọn yóò fi kọ orin pẹ̀lú ẹ̀fẹ̀ lórí nǹkan tí ó ṣe.

Bákan náà ni pé, àwọn ohun èlò orin kúlúmbú, Èèwọ̀ ni fún obìnrin láti kọjá lórí rẹ̀. Bí obìnrin bá kọjá lórí àwọn ohun èlò Kúlúḿbú bí i ìlù. Ìlù náà lè fà ya tàbí kí ó má dùn-ún mọ́ rárá. Èèwọ̀ mìíràn ni pé, àwọn ẹgbẹ́ Kúlúḿbú wọn kò gbọ́dọ̀ múra ni ìta gbangba tàbí ojú-agbo, Nítorí pé kì í jẹ́ kí wọ́n níyì tí wọ́n bá ṣe èyí.

**Ìgbéṣẹ̀ ijó Kúlúḿbú**

ìwádìí tí a ṣe pẹ̀lú àwọn tí ó ń jó ijó orin Kúlúḿbú jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé Orísìí ijó mẹ́ta tàbí ìgbéṣẹ̀ ijó mẹ́ta ni ó wà nínú Orin Kúlúḿbú.Àwọn ìgbéṣẹ̀ náà kete, sáḿbà/agẹ̀ Àlẹ̀mọ́

**Kete**

Nígbà tí wọ́n bá fẹ́ jọ Ijó Kúlúḿbú, kete ni ó máa síwájú pẹ̀lú abọ́ lílù lọ́wọ́ tí yóò máa dún sẹe,sẹẹ, sẹe àwọn tí ó ń jó ijó yìí yóò máa gbé ẹsẹ̀ márùn-ún, márùn-ún pẹ̀lú ìwọ́hùn ìlù lílù.

Sáḿbà tàbí agẹ̀

Sáḿbà tàbí agẹ̀ ni ó tẹ̀lẹ̀ kete nígbà tí wọ́n bá ń jó ijó Kúlúḿbú. Ìgbésẹ̀ agẹ̀ jẹ́ ijó alákọjú sí ara ẹni kọjú -sími, kí n kọjú sí ẹ pẹ̀lú ẹsẹ̀ gbígbé ní mẹ́ta mẹ́ta.

Àlèmọ́

Ìgbésẹ̀ kẹta nínú ijó orin Kúlúḿbú ní Àlèmọ́.Ìgbésẹ̀ yìí ni ó máa ń gbẹ̀yin Ìgbésẹ̀ orin Kúlúḿbú. Tí wọ́n bá ti ń jó ijó Kúlúḿbú lọ ní bàrúwá, ìyẹn tí ó ń gbe orin yóò fún feere tí ó wà lọ́rùn rẹ̀, yóò wá máa kọ orin báyìí

Ẹ pa yee
Olóde ẹsẹ̀
Ẹ pàjó dà
Àwa ń paradà
Olóde ò pé ká má ṣeré.

Nínú àyọlò orin òkè yìí,ìlà kìn-ín-ní sí èkejì ni ó jẹ́ ìjúbà lẹ́nu ẹni tí ó gbé orin. Ní èyí tí ó túmọ̀ sí pé, ó ń júba àwọn àgbààgbà tí wọ́n tí kọ́ jẹ́ olórin Kúlúḿbú kí ó tó bẹ̀rẹ̀ eré. Ìlà kẹta sì ìparí orin òkè yìí túmọ̀ sí pé kí àwọn tí ó ń jó ní ojú-agbo eré pá ijó tí wọ́n jó dà, kí wọ́n mú ara ijó mìíràn wọ. Lẹ́yìn tí àwọn tí ó ń jó ijó Kúlúḿbú bá ti gbọ́ irúfẹ́ orin wọ̀nyìí, wọn máa yọ ní méjì méjì, ìyẹn àwọn ọkùnrin tí wọ́n múra bíi obìnrin tí wọ́n ń jó . Wọn yóò kọjú sí ará wọn pelú ijó lẹ́sẹ̀.bí wọ́n ṣe ń jó, tí wọ́n kọjú sí ara wọn yìí ni wón yóò máa ko mọ́lẹ̀ tí ìlù yóò sì máa ké kíkan -kíkan. Bí wọ́n ṣé ń jó yìí ni inú àwọn òǹworan yóò máa dùn yìkàn, tí wọn yóò sì máa ná àwọn oníjó Kúlúḿbú lówó. Lẹ́yìn èyí ni gbogbo wọn yóò jọ jó àjópọ̀ tí wọ́n yóò sì kọ orin ìdágbére báyìí pé

lilé Ẹ ya relé
Ẹgbẹ́ orin
ilé ẹ ya relé
Ègbé Àwa relé wa o
Béẹ̀ ni àwa relé wa o o

Lẹ́yìn orin yìí ni àwọn oníjó orin Kúlúḿbú, wọn yóò tó lọ́woọ̀wó lọ sí inú ilé tàbí ibi tí won yóò ti paradà bí i egúngún.

**Ìgbáradì fún Orin Kúlúḿbú**

Tí òde orin kúlúḿbú bá yá, ó ní ọ̀nà tí àwọn olórin kúlúḿbú ń gbà múra. Ìmúra wọn yìí gan-an ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí ì ọ̀nà ìsínijẹ àti ìfinisẹ̀fẹ̀ ẹ̀dá àwùjọ. Nínú ìgbáradì orin kúlúḿbú, àwọn ọkùnrin ní wọn máa ń múra jù lọ. Àwọn ọkùnrin, wọn yóò wọ aṣọ obìnrin pẹ̀lú bèbè àti ìlẹ̀kẹ̀ ni ìbàdí. Lẹ́yìn èyí ni wọn yóò kó fóòmù sí àyà. Àyà wọn yóò ruké bí í ọmú obìnrin. Wọn yóò fi yẹtí sí etí, èyí fún ẹni tí ó bá lu etí láàárín wọn. Àwọn obìnrin tí ó wà láàárín wọn ní yóò bá àwọn ọkùnrin wọn dirun lẹ́yìn èyí ni wọn yóò lé tìróò sí ojú méjèèjì pẹ̀lú àtíkè lójú. Gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyìí ni kò kí ń jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀ pé ọkùnrin ni wọ́n. Àwọn obìnrin wọn yóò wọ ìró àti bùbá pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan asaralóge. Irun tí àwọn ọkùnrin bá dì náà ni àwọn obìnrin wọn náà yóò dì. Èyí ni kì í jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ ìyàtò láàárín obìnrin àti ọkùnrin wọn ní ojú agbo-eré nígbà tí wọ́n bá ń ṣe eré tàbí nígbà tí wọ́n bá ń jó ní ojú-agbo-eré. Lẹ́yìn tí wọ́n bá múra báyìí tán, gbogbo wọn yóò mú ìrùkẹ̀rẹ̀ dání láti fi gbọ́wọ́ ijó wọn lẹ́yìn. Lẹ́yìn èyí ni wọn yóò tò lọ́wọ́ọ̀wọ́, jáde níbi tí wọn tí múra ó di ojú agbo-eré. Ìwádìí fi hàn pé wọ́n ti máa ń múra nílé kí wọn tó lọ sí ibi tí wọn yóò ti ṣe eré.

**Àwọn Ohun Èlò Orin Kúlúḿbú.**

Àwọn ohun èlò tí wọ́n máa ń lọ fún orin kúlúḿbú ni ó máa ń jẹ́ kí àwọn òǹwòran àti àwọn oníjó kúlúḿbú máa gbádùn rẹ̀. Lára àwọn ohun èlò orin kúlúḿbú ni

Ìrùkẹ̀rẹ̀
- ìyá ìlú
- ìlú àkọ́gbé
- omele
- àwo tàbí abọ́
- Asọ eré
- Awọ ìgbàlà

**Ìrùkẹ̀rẹ̀**

Ọkàn lára ohun èlò kúlúḿbú ni Ìrùkẹ̀rẹ̀. Ìrùkẹ̀rẹ̀ yìí ni wọn máa ń lò fún dídá orin. Wọn a máa ṣe iṣẹ́ sí ìdí Ìrùkẹ̀rẹ̀ fún ẹni tí ó dá ọrùn, kí ó lè baà tètè rántí orin tí ó fẹ́ kọ. Bákan náà Ìrùkẹ̀rẹ̀ yìí tún jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí ẹni tí ó lé orin ń gbà bá àwọn tí ó ń jó sọ̀rọ̀ kâì lo ọ̀rọ̀ ẹnu.

Ìyá ìlù

Ìyá ìlú ló tóbi jù lọ nínú gbogbo àwọn ìlú tí àwọn oníkúlúḿbú máa ń lù ù. Ojú méjì ni ìlú yìí ní bẹ́ẹ̀ sì ni ọwọ́ méjì ni wọn fi máa ń lù ú. Wọn a máa fi irọ̀ sí ojú ìlú láti lè jẹ́ kí ó dún dáadáa. Ìyá ìlú yìí ni wọn máa ń fi bá àwọn tí ó ń jó sọ̀rọ̀ láti lè mọ ìgbésẹ̀ tí ó kàn nínú ijó tí wọ́n ń jó.

**Ìlù àkọ́gbé**

Ìlù yìí kò tóbi tó ìyá ìlù rárá, ojú méjì ni òun náà ni, ṣùgbọ́n wọ́n máa ń kọ́ ohun sí èjìká ni gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀ ṣe rí ọwọ́ ni wọ́n máa ń fi lu ìlù yìí. Ègbè ló máa ń ṣe lẹ́yìn ìyá ìlù.

**Omele**

méjì ni omele yìí ọkàn jẹ́ omele kékeré nígbà tí èkejì jẹ́ Omole ńlá. Omele ńlá àti kékeré ní ojú agbo-eré. Àwọn omele yìí ní ó máa ń jẹ́ kí ìwọ́hùn ìlù fìdí múlẹ̀ dáadáa.

**Àwo tàbí Abọ́**

Ọkùnrin máa ń lu àwo abọ́, obìnrin lù ú ọmọdé àti àgbàlagbà náà máa ń lu àwo tàbí abọ́, ṣùgbọ́n obìnrin ni ó máa ń sáábà lù ú jù lọ. Èyìn abọ́ ni wọ́n fi máa ń gbá ọwọ́ òsì tí yóò sì máa dún ṣée,ṣée,ṣée nígbà tí wọ́n bá ń ṣeré lójú agbo. Abọ́ yìí jé abọ́ tí wọ́n dá etí rẹ̀ lu. Tí wọ́n sì fi òrùka tàbí òjé sí etí rẹ̀. Èyí ni ó mú kí ó máa dún ṣée ṣée ṣée

**Aṣọ eré**

aṣọ eré ni aṣọ tí àwọn òǹkọrin lọ láti fi ṣe ìsínije àwọn ẹ̀dá àwùjọ. Aṣọ eré gan-an ni ó ń tọ́ka sí irú ẹ̀dá àwùjọ tí wọ́n fí ń ṣe ẹ̀fẹ̀ ní ojú agbo-eré. Aṣọ eré yìí ni ó jẹ́ ki Orin Kúlúḿbú yàtọ̀ sí orin mìíràn ní Ọjà-Ọ̀dàn. Nínú Orin Kúlúḿbú àwọn ọkùnrin a máa wò aṣọ obìnrin láti fi ṣe ìsínijẹ àwọn ẹ̀dá àwùjọ kan.

**Awọ ìgalà**

Awọ ìgalà ni wọ́n fí máa ń ṣe ìlù Kúlúḿbú.



**Àwòrán Àwọn Ọmọ Ẹgbẹ́ Kúlúḿbú àti Ohun Èlò Eré wọn**
**ORÍSUN-ÌMỌ̀ -: Oko Ìwádìí Olùwádìí ní Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn (06-02-2025)**



**Ọ̀nà ìfinisẹ̀fẹ̀ àti àwùjọ nínú Orin Kúlúḿbú**

onírúurú ọ̀nà ni àwọn olorin Kúlúḿbú ń gbà fi ẹ̀dá àwùjọ ṣe ẹ̀fẹ̀ nínú Orin wọn. Ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ní pé, àwọn ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ni àwùjọ ni wọ́n máa ń mú lọ láti fi ṣe ẹ̀fẹ̀ ninu orin wọn. Ìmúra àwọn ọkùnrin wọn tí wọ́n múra bí obìnrin, ọ̀nà ìfinisẹ̀fẹ̀ kan ni pàtó, tí ó jẹ pé, nípa ìwà tí ó ń hù, àwọn òǹworan yóò máa rò wí pé ẹ̀fẹ̀ lásán-làsàn ni. Bẹ́ẹ̀ sì ni nnkan ki sí ẹsẹ ràgó, a je ẹran tán, ó tún ku egungun. Èyí túmọ̀ sí pé, ọ̀nà ìfínisẹ̀fẹ̀ nínú Orin Kúlúḿbú jẹ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdánilárayá fún àwọn ẹ̀dá àwùjọ lára ọ̀nà ìfínisẹ̀fẹ̀ àti ìjanu àwùjọ nínú Orin Kúlúḿbú láti rí.

**Ìbà jíjú**

Yorùbá ní pé ohun kóhun tí a ba fẹ́ ṣe dandan kí a kọ́kọ́ fi Elédùmarè síwájú. Yorùbá gbàgbọ́ pé tí ẹ̀dá kan bá ń pète láìjúbá, bí ìgbà tí onítọ̀hún ń ṣe ìgbéraga àti àfojúdi ni. Ìdí nìyí ni ó fi jẹ́ pé, kò sí nǹkan ti awọn Yorùbá bá fẹ́ ṣe, wọ́n ka ìjúbà kún ohun tí ó ṣe pàtàkì láti kọ́kọ́ ṣe, kí wọ́n tó dá ọwọ́ lé ohunkóhun. Orímóògùnjẹ́ 2012 tilẹ̀ fi ìdí èyí múlẹ̀ pé;

> Ní àwùjọ Yorùbá, ìbà jẹ́ nǹkan tó pọn dandan láti ṣe fún ẹ̀dá tó bá fẹ́ dáwọ́lé nǹkan, pàápàá nǹkan tí ẹni náà mọ̀ pé àwọn kan ti ṣe irúfẹ́ rẹ̀ rí. ìbà kì í se nǹkan kèrémí ní àarin àwọn Yorùbá; ó jẹ wọ́n lógún gan-an, kódà, wọn a máa

> kan oró ẹni tí kò bá júbà mọ́nú. Ìjúbà ni a rí gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan pàtàkì lára ìṣe Yorùbá tó máa ń mú ẹ̀dá mọ ibi tí iṣẹ́, ìṣe, ìdílé àti ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ti ṣẹ̀ wá. Ó jẹ́ dúkìá kò-ṣe-é-má-nì-ín tó wà fún ìṣọ́rí, tí kì í jẹ́ nǹkan tí ẹ̀dà ń ṣe lọ́wọ́ hun ún. Abájọ tí Yorùbá fi ń sọ pé 'Àdáṣe níí hunni, ìbà ò gbọdọ̀ hunmọ ènìyàn. Àwọn Yorùbá tún ka ìbà sí ọ̀nà tí wọn ń gbà tẹríba tàbí wárí fún Olódùmarè, àwọn irúnmọlẹ̀, àwọn alayé, àgbà iwájú, ẹgbẹ́ òun ọ̀gbà àti àwọn tó ń bọ̀ lẹ́yìn. Ìdí rèé tí wọ́n fi ń sọ pé 'mo júbà ará iwájú káyé ó le yẹ mí, mọ ṣèbà èrò ẹ̀yìn, kẹ́yẹ má baà yọ̀wú mi jẹ', Ẹni tó bá ń tẹríba fún ọmọ aráyé, nǹkan yóòwù kí onítọ̀hún dáwọ́lé, ó di dandan kí ó kẹ́sẹ járí; tirẹ̀ ni yóó sì máa wu ọmọ adáríhurun. Bákan náà ní àwọn Yorùbá gbà pé ìbà jẹ́ ọ̀nà ẹ̀rọ tí wọ́n ń lò láti bu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún ẹni tó jẹ́ aṣáájú nǹkan tí wọn ń ṣe. ọ̀rọ̀ àánú, ire àti ìre yóó sì máa jáde lẹ́nu ẹni tí wọ́n ń fìbà fún. Ìdí sì rèé tí wọ́n fi mú ìbà ní ọ̀kúnkúndùn kí àṣeyọrí àti ìdágìlọ ire baà lè jẹ́ tẹni. Lọ́rọ̀ kan ṣá, a lè sọ pé ìba-jíjú jẹ́ okùn orí-ire àti ìdùnnú fún ọmodé, àgbà, àwọn òòṣà àti nǹkán ẹlẹ́mìí mìíràn ní àwùjọ Yorùbá. èyí ló jẹ́ kí a pe ìba ní kẹ̀kẹ́ ìhìn-rere fún Lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.

Nínú àyọlò òkè yìí, a ri pé ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí ó fẹ́ràn ìtẹríba àti ibọ̀wọ̀fún púpọ̀. Ó hàn gbangban nínú àyọlò òkè yìí pé, àwọn Yorùbá gbà pé ìbà jẹ́ ọ̀nà ẹ̀rọ tí wọ́n ń lò láti bu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún ẹni tó jẹ́ aṣáájú nǹkan tí wọn ń ṣe. Yorùbá máa ń bí ekòló bá júbà ilẹ̀, ilẹ̀ á lanu. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé, bí a bá fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ohun gbogbo a gbọ́dọ̀ wúre tàbí gba àdúrà . Ìwúre tàbí àdúrà yìí ni àwọn apohùn kà sí ìjúbà. Ìjúbà yìí ṣe pàtàkì nínú Orin Kúlúḿbú. Tí àwọn olorin Kúlúḿbú bá ti dé ojú agbo-eré kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ ohunkóhun ìjúbà ni wọ́n máa ń fi ń síwájú . Bí wọ́n ṣe ń júbà fún elédùmarè, ní wọ́n yóò máa júbà fún àwọn aláṣekù, àwọn ajunilọ, àwọn òǹworan pàápàá jù lọ ẹni tí ó pé wọ́n sì òde aré. Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

Ìbà àgbó<br>
Àgbó mo júbà<br>
ìbàà adẹ̀dàá<br>
Ìbàà asẹ̀dàá<br>
Mo sèbá àgbáyé<br>
Mo sèbá Aláṣẹkù<br>
ìbàà lọ́wọ́ akọ́se<br>
. Ìbàà lọ́wọ́ apètepèrò

Nínú àyọlò òkè, a ó ò ṣe àkíyèsí pé, adárin orin náà júbà lọ́wọ́ elédùmarè, àwọn òkú ọrun,àwọn tí ó ti ń kọ orin Kúlúḿbú tẹ́lẹ̀ àti àwọn tí ó pè wọ́n sí oko aré. Ní abala ìjúbà yìí àwọn Alárè Kúlúḿbú wọn kò ní ti ì bẹ̀rẹ̀ orin kankan, gbogbo wọn yóò dúró ní ojú agbo, bí alérin wọn bá ti bẹ̀rẹ̀ ìjúbà pẹ̀lú ìrùkẹ̀rẹ̀ lọ́wọ́, leyin ti wọ́n bá júbà tán ni wọ́n yóò bẹ̀rẹ̀ orin ìfínisẹ̀fẹ̀ wọn.

**Orin Ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìfínisẹ̀fẹ̀**

àwọn òn orin Kúlúḿbú a maa kọ onírúurú àwọn ìbàjẹ́ tí àwọn ènìyàn hù nínú àwùjọ láti fi ṣe ẹ̀fẹ̀ nínú Orin wọn. Ìgbàgbọ́ wọn ní pé ọ̀nà tí àwọn lè gbà dẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ bẹ́ẹ̀ ṣíṣe àgbékalẹ̀ orin ẹ̀fẹ̀ tí yóò ṣe àkóónú onírúurú àwọn ìwà ìbàjẹ́ náà. Èyí ni yóò jẹ kí àwọn tí ń hu ìwà ìbàjẹ́ wọ̀nyìí dẹ́kun rẹ̀ láwùjọ . Ẹ wo àpẹẹrẹ orin Kúlúḿbú ìsàlẹ̀ yìí.

Ẹ ò rí wọn ní

Alágbè rè aya
Lílé : Wẹ̀dẹ̀ wẹ̀dẹ̀ lábẹ́ igi
Ègbè: Wẹ̀dẹ̀ wẹ̀dẹ̀ lábẹ́ igi
Lílé : Aya sákírù lábẹ́ páákí
Ẹ ń fepo jẹ su
Ègbè: Síínú eepo
Síínú eepo
Lílé Tòòró tòòró o ó
Ẹ ń ṣòwò nàbì
Ègbè Síínú eepo
Síínú eepo

Nínú ayọlò orin Kúlúḿbú òkè yìí, a rí àpẹẹrẹ ìwà àgbèrè tí àwọn olórin Kúlúḿbú ṣe àfihàn rẹ̀ ìbẹ̀rẹ̀ orin òkè yìí ń tọ́ka sí ìwà àgbèrè. Wọ́n fi yé wa pé, abẹ́ igi àti abẹ́ igi páki ni wọ́n tí ń bá ìyàwó sákírù sún. Bí wọn ṣe kọ irú orin báyìí ni àwọn oníjó Kúlúḿbú wọn yóò máa fi ṣe ẹ̀fẹ̀ ni ojú agbo-eré. Ọ̀kan nínú wọn yóò dúró gẹ́gẹ́ bí obìnrin alágbèrè ìyàwó Sákírú gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe tọ́ka rè nínú àyọlò òkè yìí. Èkejì yóò dúró gẹ́gẹ́ bí ọkùnrin tí ó ń bá ìyàwó Sákírú ṣe àgbèrè . wọn yóò máa ìwà àgbèrè yìí ṣe ẹ̀fẹ̀ ní ojú agbo. Bí wọ́n ṣé ń ṣe èyí ní àwọn òǹwòran yóò máa rín ẹ̀rín -arin-tàkìtì. Àwọn tí ó bá mọ̀ nípa ọ̀rọ̀ sákírù àti ìyàwó rẹ̀ yìí wọn tí mọ̀ pé kì í ṣe ẹ̀fẹ̀ lásán. Èyí jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí àwọn ènìyàn máa ń fi ń kó ara wọn ní ìjánu láti má hu ìwà ìbàjẹ́ tàbí ìwà èérí kankan nítorí wọ́n mọ̀ pé, bí àwọn bá hu ìwà ìbàjẹ́ tàbí ṣe nǹkan àṣírí tí etí kò-ṣeé- gbọ́, ìta gbangba ni àwọn olórin kúlúḿbú yóò ti tú àṣírí àwọn

**Ìfinisẹ̀fẹ̀ gẹ́gẹ́ bí i ìmọ̀ràn**

ìwádìí tí a ṣe nípa orin kúlúḿbú fi hàn pé, kúlúḿbú kìí kàn-án ṣe fún awẹ́wàá nìkan, bí kò ṣe fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí ó gbọngbọn. Orin kúlúḿbú tún máa ń jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì láti fi gba ẹni ní ìmọ̀ràn pàápàá jù lọ àwọn àwùjọ kan tí èdè -aìyedè fi ṣẹlẹ̀ láàárín wọn. Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ àpẹẹrẹ

Lílé : Hà ké ó ṣẹlẹ̀
gbogbo ara yewa
Hàà, ó ṣẹlẹ̀?
Gbogbo ará yewa

Ègbè : Hà, ké ó ṣẹlẹ̀ ẹ ẹ

Lile : ọgbọ́n kò yọ gbọn
èdè kò yèdè ń bẹ̀

Ègbè : Hà ké ó ṣẹlẹ̀ ẹ ẹ
Hà ké ó ṣẹlẹ̀ ẹ ẹ

Lílé : Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Ègbè: Ẹ gbìmọ̀ pọ

Lílé : Ẹ fọwọ́sowopọ̀ ẹ ẹ

Ègbè : Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ
Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Lílé : À kò níná kó kárí

Ègbè Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Lílé : Iṣẹ́ là rí kò sówó

Ègbè : Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ
Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Lílé : Ẹ jẹ́ á gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Ègbè : Ẹ gbìmọ̀ pọ ẹ ẹ

Nínú orin àyọlò òkè yìí, a rí àpẹẹrẹ orin ìmọ̀ràn tí ó ń jẹ yọ nínú orin kúlúḿbú. Ìlà kíi-ín-ní ni ó jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìbéèrè tí òǹkọrin kúlúḿbú béèrè pé, Ẹyin ará yewa kí lẹ ní ó ṣẹlẹ̀. A rí pé ìṣẹ̀lẹ̀ kan ló ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn láàárín yewa àti ọjà-ọ̀dàn nípa iná népà, tí a bá lọ wo ìlà keèógún nínú àyọlò òkè yìí. Orin àyọlò òkè yìí ń gba àwọn ará yewa àti ọjà-ọ̀dàn ní ìmọ̀ràn pé, kí wọ́n má jẹ́ kí èdè-àìyedè bé sílẹ̀ láàárín àwọn méjèèjì. Wón kò bá fi ọwọ́ sọ ọwọ́ pọ̀ fún ìdàgbàsókè ìlú. Èyí jẹ́ yọ ní òpin ìlà àyọlò òkè yìí. Orí kì í balẹ̀ kó má yìí nǹkan ni orin kúlúḿbú. Bí wọ́n ṣé ń kọ àwọn orin yìí ni wọn yóò máa fí ṣe ẹ̀fẹ̀ fún àwọn ènìyàn àwùjọ ní ojú agbo-eré. Tí àwọn tí ọ̀rọ̀ kan bá tilẹ̀ gbó irú orin báyìí ọkàn wọn lè rò pẹ̀tẹ̀, tí wọn yóò sì wá ọ̀nà àbáyọ sí nǹkan tí ó ń ṣẹlẹ̀.

**Èébú gẹ́gẹ́ bí í ìfinìṣẹ̀fẹ̀**

Ní òpò ìgbà ni orin kúlúḿbú máa ń jẹ́ èébú. Bóyá ẹ̀dá kan hu ìwà èérí, ọ̀bùn tàbí kò ní iṣẹ́ ni apá. Tí àwọn olórin kúlúḿbú bá dé ojú agbo-eré. Irú ẹ̀dá báyìí wón lè fi ṣe ẹ̀fẹ̀ láti dẹ́kun irú ìwà báyìí nínú àwùjọ wọn Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

Lílé Mo rímí Ẹlẹ́dẹ̀ níta rẹ̀
Mo rímí Ẹlẹ́dẹ̀ níta rẹ̀
Ọ̀bùn ìyàwó, ó lé góńgó
Ègbè : Ọ̀bùn ìyàwó, ó lé góńgó
Lílé : Mo rímí Ẹlẹ́dẹ̀ níta rẹ̀
Àyọkà, ẹ máa gbálẹ̀ o o
Ẹ máa gbálẹ̀ o o o

Ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí ó korira ìdọ̀tí, nítorí èyí ni ó fí jẹ́ pé tí wọ́n bá rí ẹ̀dá tí ó hú ìwà èérí wọn yóò máa pè é ní Ọ̀bùn. Àyọlò orin òkè yìí ṣe àfihàn ìwà Ọ̀bùn. Ní ìlà kì í-ín-ní nínú àyọlò òkè yìí ni ó ṣe àfihàn pé ìgbé Ẹlẹ́dẹ̀ ni wọ́n máa ń rí níta ìyàwó ilé kan kìí wá se ìgbé nìkan, bí kò ṣe pé ìyàwó ilé náà kì í gbálẹ̀ rárá. Ìlà kẹfà ni ó ń tọ́ka sí eni ti wọn fí orin kúlúḿbú báwo, ìyẹn Àyọkà ìyàwó ilé ni Àyọkà, ṣùgbọ́n ó ní Ọ̀bùn púpọ̀, kì í gbálẹ̀ bẹ́ẹ̀ sì ni ìdọ̀tí a máa pò ní iwájú ìta ilé rè. Àwọn olórin kúlúḿbú mọ̀-ọ́n-mo lọ orin yìí ni ìgbàgbọ́ pé bí àwọn bá dá orúkọ ẹni tí ó ń hu irú ìwà yìí, àwọn tí ó ń gbìyànjú

**Ìdánilárayá gẹ́gẹ́ bí i ìfinìṣẹ̀fẹ̀**

nínú orin kúlúmbú.kìí ṣe ìdanilẹ́kọ̀ọ́ nìkan ni ó máa ń jẹ yọ nínú orin kúlúmbú.A ri pé ìdí tí àwọn fi fẹ́ràn orin yìí láti máa gbọ́ tàbí láti máa fi máa wò ni pé,ó ń fún wọn ní ìdùnnú,ó ń mú oríyá bẹ́ẹ̀ sì ni a máa mú inú wọn dùn. Àkíyèsi fi hàn pé ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé,àwọn tí olórin kúlúmbú kọ orin bú máa ń wà ní ojú agbo-eré, ṣùgbọ́n nítorí ìdúnnú tí wọ́n ń rí níbẹ̀. Gbogbo nnkan tí wọ́n bá rí ṣe ni wọn yóò máa ká mọ́ ara.pọ̀tọ̀pọ́tọ̀ tí a nà ní pọ̀pá ni ọ̀rọ̀ orin kúlúmbú ẹni tí ó bá ta bá,kí ó má fi bínú ni. nígbà tí wọ́n bá ń kọ orin kúlúmbú tí ó jẹ mọ́ ìdánilárayá ni gbogbo nnkan yóò yàtọ̀.orin yóò yí padà,ìlù yóò paradà àwọn tí ó ń jó pàápàá wọn yóò mú ara wọn ní méjì-méjì pẹ̀lú ara ijó ní ẹsẹ̀ wọn. Ẹ wo àpẹẹrẹ orin yìí

lilé : Àgò Àgò
Ègbè: Àgò Àgò
lilé : Mo lè bónílé ṣeré
Ègbè: Àgò àgò
lilé Mo lè gbólóde ṣòde
Ègbè: Àgò àgò
lilé. : Mo bólóde ṣòde òní o
Ègbè: Àgò àgò

Nínú àyọlò orin kúlúmbú òkè yìí a rí àpẹẹrẹ pé orin tí ó ní í ṣe pẹ̀lú amóríyá ni orin náà ìlà kìn-ín- ní sí èkejì nínú àyọlò òkè yìí ni ó jẹ́ gẹ́gẹ́ bíi ìpàjùbà ijó sílẹ̀ fún àwọn ònwòran. Tí àwọn ònwòran bá ti gbọ́ irú ìṣíde báyìí,wọn ti mọ̀ pé ijó àjó-tàkìtì ni ó kù. Ní abala orin kúlúmbú ajẹmọ́ ìdánilárayá yìí, ni àwọn ònwòran ti máa ń kópa nínú eré nípa ijó jíjó,owó níná tàbí ìgbóríyìn fún àwọn eléré kúlúmbú.

**Orin Kúlúḿbú gẹ́gẹ́ bí i Ìbọ̀wọ̀fún.**
ọ̀kan lára àkóónú orin kúlúmbú ni ìbọ̀wọ̀fún.Tí àwọn olórin kúlúmbú bá ti wà ní ojú agbo-eré,tí wọ́n ti ń ṣe eré lọ,wọn a máa fi orin kúlúmbú ṣe ìbọ̀wọ̀fún fún àwọn àgbàlagbà tí wọ́n wà ní ojú agbo-eré. Àkíyèsi fi hàn pé ní ọ̀pọ̀ ni àwọn tí wọ́n fi orin ṣe ìbọ̀wọ̀fún lè jẹ́ ọba tàbí ìjòyè.Ẹ wo àpẹẹrẹ

Ẹ wólè ká kíba
Adé lóde ọba ká ṣí fìlà
Ẹ wólẹ̀ ká kí ba
Àti wòde ọba ká ṣí gèlè
Ẹ wólẹ̀ ká kíba,ẹ bọ́ bàtà

Nínú àpẹẹrẹ orin òkè yìí, a ri pé ìlà kejì ni ó ń tọ́ka sí ẹni tí àwọn olórin kúlúmbú ṣe ẹ̀pọ́n fún ní ojú agbo-eré. Àpẹẹrẹ òkè yìí fi hàn pé ọba dáadáa ni ọba náà,ó sì jẹ́ olóòótó ènìyàn. Ìwádìí fi hàn pé, tí ó bá jẹ́ àgbà tí ò to ìlú ni àwọn eléré kúlúmbú rí,wọn yóò tú gbogbo àṣírí rẹ̀,wọn yóò sì fi hàn gẹ́gẹ́ bí adarí tí ò to ìlú. Gbogbo àwọn nnkan tí wọ́n ń ṣe nìyí tí ó fi jẹ́ àwọn ará ìlú máa ń ṣọ́ ara wọn láti hu àwọn ìwà kan nítorí wọ́n mọ̀ pé,bí àwọn bá wu ìwà ìbàjẹ́, gbangba ni àwọn yóò ti gbọ́ ọ̀rọ̀ àwọn.

**Ìwúre nínú Orin Kúlúmbú**
Ní ọ̀pọ̀ ni ó jẹ́ pé àwọn olórin kúlúmbú máa ń fi orin wure tàbí ṣe àdúrà fún ẹni tí ó ná wọn lówó ní ojú agbo-eré tàbí tí wọ́n bá rí ènìyàn kan nínú àwùjọ.Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

Gbogbo ònìyàn ìyó wa,ẹ máa ṣe o
A feléyì san re rẹ̀ fúnra ẹni
Gbogbo ònìyàn ìyò wá,ẹ máa ṣé o
A feléyì san re rẹ̀ fúnra ẹni
Inú pe a ń ṣègbéyàwó
À ń sile laa máa fi sanrẹ̀ fún ara ẹni
Kà kàn nìkan o
Ikú àìtọ́jọ́
Kà kàn nìkan
Àìsàn yée kò gbóògùn
Ogun à séré pè
ká koni tọmọtọmọ.

Àyọlò orin òkè yìí a rí pé ìwúre ni àwọn olórin kúlúḿbú ṣe fún gbogbo àwọn tí ó wà ní ojú agbo-eré. Ìlà kíi-ín-ní sí ẹ̀kẹfẹ̀ ni ó ń tọ́ka sí bí olórin kúlúḿbú ṣe ń gba àdúrà pé, gbogbo wa ni a óò péjúpẹ́ṣẹ̀, bímọ, ṣègbéyàwó bẹ́ẹ̀ sì ni a kò ní fi fi ọjọ́ ọlọ́jọ́ lọ. Ìlà kẹ̀ẹwà títí dé

òpin ìlà àyọlò orin òkè yìí ni ó ń tọ́ka sí pé olórin kúlúḿbú ń ṣe àdúrà pé, ikú kò ní pá ẹnì kọ̀ọ̀kan bẹ́ẹ̀ sì ni àìsàn tí ò gbóògùn kò ní wọ ilé tò wá. Bí àwọn olórin kúlúḿbú bá ń ṣe irúfé àwọn orin báyìí ni àwọn òǹwòran yóò máa ṣe àmí, tí inú gbogbo wọn yóò sì máa dún yìnkìn.

**Orin kúlúḿbú gẹ́gẹ́ bí i Orin Ìdágbére.**

Orin ìdágbére ni orin tí wọ́n máa ń kọ́ nígbà tí eré bá ti parí. Orin ìdágbére jẹ́ ọ̀kan lára àwọn kókó inú orin kúlúḿbú tí wọ́n máa ń lọ láti sọ fún àwọn ènìyàn pé àwọn tí ń lọ sí ilé àwọn. Ẹ wo àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí

Àwa ń relé o
Àwa ń relé o
Ọmọ ọba kìí rìn iganjo àilè ń lẹ́
. Àlàó bó tó ìlò lailo

Nínú àyọlò orin òkè yìí ṣe àfihàn orin ìdágbére tí àwọn olórin kúlúḿbú máa ń kọ́ tí wọ́n bá ti parí eré won ìlà àkókò nínú àyọlò òkè yìí ni ó ń ṣe ìtọ́kasí pé eré tí àwọn olórin kúlúḿbú tí ṣe tí tán, wọn tí fe máa lọ sí oríkì tí olórin kúlúḿbú kí ara rẹ̀ láti fi hàn pé ìran àwọn ni ó máa ń kọ́ orin yìí àti pé ìdílé àwọn ni ó mú gẹ́gẹ́ bí í iṣẹ́ òòjó. Bí wọ́n bá ti kọ orin yìí kan ní wọn yóò máa tò lọ sí ọ̀nà

**Ìkádìí**

Ó hàn gbangba pé orin Kúlúḿbú ní Ọjà-Ọ́dàn ní agbègbè Yewa wà fún ìdàgbàsókè àwùjọ. Àwọn àkóónú orin Kúlúḿbú máa ń tọ́ka sí pé, a gbọdọ̀ dẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ nínú àwùjọ. Ọ̀nà tí a sì lè gbà dẹ́kun rẹ̀ ni kí á máa fi oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ ṣe ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ nínú orin wa. Kí á sì máa fi orin gbóríyìn fún àwọn tí ó bá ṣe dáadáa nínú àwùjọ. Nítorí Yorùbá bọ̀ wọ́n ní Yinni- Yinni ni kí ẹni lè ṣe òmíràn. Iṣẹ́ Ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, orin gbọ́dọ̀ lè máa tọ́ àwọn ènìyàn sọ́nà nípa kíkópa nínú ìdàgbàsókè àwùjọ wọn. Iṣẹ́ yìí fi hàn pé, kí àwọn ènìyàn máa kópa nínú orin tí yóò mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ. Bákan náà ni pé, pépà yìí fi ẹnu ọ̀rọ̀ jóná pé, orin tí kò bá ti ní ìtumọ̀ kì í ṣe orin Yorùbá. Orin Yorùbá gbọ́dọ̀ ní ìtumọ̀ tí ó mọ́yán lórí, ipa tí ó ń kó lórí dídẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ àti ọ̀nà tí ó ń gbà mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ Yorùbá.

**Àkójọpọ̀ Orúkọ Ìwé**


Abímbọ́lá, W. (1977a) *The Study of Yorùbá Literature: An Assesment* An Inaugural lecture Delivered at the University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀, Ifẹ̀, University of Ifẹ̀ Press.

Aṣíwájú, A.I. (1976) "Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Songs as Source of Western Yorùbá History". *Yorùbá Oral Tradition*, Wándé Abímbọ́lá (ed.) Department of African Languages and Literature, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀: 98-105. Mimeograph.

Awóbùlúyì, O. (1983) (ol.), Yorùbá Meta Language. Ìbàdàn: U.P.L.

Awobuluyi, O. (1990) *Yorùbá Metalanguage*. Vol. II. Ìbàdàn: University Press

Beier, Ulli and Gbadamọsi, B. (1959) *Yorùbá Poetry*. Ìbàdàn: Government Printers.

Church Missionary Society (1913) *A Dictionary of the Yorùbá Language*, Oxford: University Press Plc.

Olúkòjú, E.O. (1985) "Music in Religious Worship" ORITA: *a journal of Religious Studies Association of Nigeria*, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn: 118.

Olúkòjú, E.O. (1994) *The Study of Yorùbá Songs*. Ìbàdàn, Centre for External Studies. Ìbàdàn: Faculty of Education, University of Ìbàdàn.

Orímóògùnjẹ́ (1999) *Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá* Lagos, Káróhunwí Nig. Entprises.

Rájí, S.M (2008) "Àgbéyẹ̀wò Ajẹmọ́-kókó Ọ̀rọ̀ àti Ìṣọ́wọ́lò-Èdè nínú Ìjálá Àbàbí Ògúndépò". Unpublished M.A Dissertation, Department of Linguistics and African Lan guages, O.A.U, Ilé-Ifẹ̀.

Rájí, S.M. (2014) “Àgbéyẹ̀wò Ojú Àmúwayé àti Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá nínú Orin Musulumi ní Ilẹ̀ Yorùbá.” Unpublished PhD Thesis Department of Linguistics and African Languages O.A.U, Ilé-Ifẹ̀.

Recebido em: 23/02/2025

Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** IBRAHIM, Wahab Adegbayi. Orin Kúlúńbú: Ọnà Ìfinịṣẹ̀fẹ̀ àti Ìjánu Àwùjọ ní Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn Yewa**.** *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial II, p. 198-210, jul./dez.2025.

**Para citar este texto (APA):** Ibrahim, Wahab Adegbayi (jul./dez.2025 Orin Kúlúńbú: Ọnà Ìfinịṣẹ̀fẹ̀ àti Ìjánu Àwùjọ ní Ìlú Ọjà-Ọ̀dàn Yewa. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial II): 198-210.